**6.** Njẹ kò ri ọ ni ọmọ-orukan ti O si dãbo bò ọ?

أَلَمْ يَجِدْكَ يَتِيمًا فَـَٔاوَىٰ ﴿٦﴾

**7.** Atipe O ri ọ ni ẹniti kò mọ̀nà O si fi ọna mọ̀ ọ?

وَوَجَدَكَ ضَآلًّا فَهَدَىٰ ﴿٧﴾

**8.** Atipe O ri ọ ni alaini O si sọ ọ di ẹni ti o ni?

وَوَجَدَكَ عَآئِلًا فَأَغْنَىٰ ﴿٨﴾

**9.** Nitorina maşe ni ọmọ-orukan lara.

فَأَمَّا ٱلْيَتِيمَ فَلَا تَقْهَرْ ﴿٩﴾

**10.** Atipe ki o maşe kanra mọ alagbe.

وَأَمَّا ٱلسَّآئِلَ فَلَا تَنْهَرْ ﴿١٠﴾

**11.** Atipe õre idẹra Oluwa rẹ, sọ ọ jade.

وَأَمَّا بِنِعْمَةِ رَبِّكَ فَحَدِّثْ ﴿١١﴾

## *(94) Suratul - Şarhi*

سُورَةُ الشَّرْحِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Njẹ Awa kò ti şipaya igbaiya rẹ fun ọ bi?

أَلَمْ نَشْرَحْ لَكَ صَدْرَكَ ﴿١﴾

**2.** Atipe Awa ti gbe ẹru wiwuwo rẹ kuro fun ọ.

وَوَضَعْنَا عَنكَ وِزْرَكَ ﴿٢﴾

**3.** Eyiti o wọ̀ ọ lọrùn.

ٱلَّذِىٓ أَنقَضَ ظَهْرَكَ ﴿٣﴾

**4.** A si ti gbe iranti orukọ rẹ ga fun ọ.

وَرَفَعْنَا لَكَ ذِكْرَكَ ﴿٤﴾

**5.** Dajudaju lẹhin inira irọrun mbẹ.

فَإِنَّ مَعَ ٱلْعُسْرِ يُسْرًا ﴿٥﴾

**6.** Dajudaju lẹhin inira irọrun mbẹ.

إِنَّ مَعَ ٱلْعُسْرِ يُسْرًا ﴿٦﴾

**7.** Nitorina nigbati o ba bùṣe ki o gbiyanju.

فَإِذَا فَرَغْتَ فَٱنصَبْ ٧

**8.** Nitorina ṣe ojukòkòrò lọ si ọ̀dọ̀ Oluwa rẹ̀.

وَإِلَىٰ رَبِّكَ فَٱرْغَب ٨

## *(95) Suratul - Tini*

سُورَةُ التِّينِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi eso ọpọtọ (Tini) bura ati eso igielepo didun.

وَٱلتِّينِ وَٱلزَّيْتُونِ ١

**2.** Ati oke ‘Sĩnĩna’ (bura).

وَطُورِ سِينِينَ ٢

**3.** Ati ilu ifaiyàbalẹ yi (bura).

وَهَٰذَا ٱلْبَلَدِ ٱلْأَمِينِ ٣

**4.** Dajudaju A da enia ni ẹ̀yà daradara julọ.

لَقَدْ خَلَقْنَا ٱلْإِنسَٰنَ فِىٓ أَحْسَنِ تَقْوِيمٍ ٤

**5.** Lẹhinna A o da a pada si àyè ti o rẹlẹ̀ jù.

ثُمَّ رَدَدْنَٰهُ أَسْفَلَ سَٰفِلِينَ ٥

**6.** Ayafi awọn ti o gbagbọ ni ododo ti o si nhuwa rere; nitorina ẹsan ti kò ni ja mbẹ fun wọn.

إِلَّا ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ وَعَمِلُوا۟ ٱلصَّٰلِحَٰتِ فَلَهُمْ أَجْرٌ غَيْرُ مَمْنُونٍ ٦

**7.** Atipe tani ẹni ti otun le pe ọ lopurọ (irẹ Annabi) nipa idajọ Ọlọhun tabi isiro lẹhinna?

فَمَا يُكَذِّبُكَ بَعْدُ بِٱلدِّينِ ٧

**8.** Njẹ ki iṣe Ọlọhun ni O mọ ẹjọ da ju gbogbo oludajọ lọ bi?

أَلَيْسَ ٱللَّهُ بِأَحْكَمِ ٱلْحَٰكِمِينَ ٨